# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE. TẸNI GBOGBO LAWA

No 772 MONDAY AUGUST 17, 1964 (2D


## Ọga OluKọ Kan Fara K'ọrin

ABẸOKUTA:- Lẹnu lọlọyi ni Ọga Olukọ kan ni ile ẹkọ giga ti Peters College, Abẹokuta ti o tun jẹ ọmọ ile Igbimọ Afunshọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Abẹokuta Ọgbẹni Ephram Agunbiade fi ara han ile ẹjọ kekere ti Abẹokuta lori ẹsun pe odaile ẹkọ kan silẹ eyiti ile iṣẹAlakoso ẹkọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun kofiọwọsi

Agbẹjọro fun ile ẹjọ na sọpe ọdarnn na tun jẹ akọwe ẹgbẹ kan ti a pe n (Ẹgba Parapọ League) eyiti ojẹ ẹka ẹgbẹ Oṣelu kan to faramọ ẹgbẹ Dẹmọ N N D P pe larin oṣu kini si oṣu kẹjọ Ọdun yi pe Ọgbẹni Agunbiade da ile ẹkọ silẹ ni ilu Abẹokuta eyiti olodi si Ofin eto ẹkọ ti Ijọpa Ipinlẹ Iwọ Orun Najiria.

Ninu ọrọ ọdaran na fun adajọ ile ẹjọ na Ọgbẹni Agunbiade sọ pe on ko jẹbi lori ẹsun ti ile ẹjọ fi kan on rara Adajọ ile ẹjọ na si sun ọjọ ti nwọn yio ma ba ẹjọ na lọ si ipari oṣu yi.

Adajọ ile ẹjọ na-si gbẹbẹ lati gba idurO Ọdaran na lori adọta Pọun (£50) ati ẹn ti yio duro fun un lori iye owo na titi Ọdaran na yio tun fi ara han ni ile ẹjọ na ni ipari oṣu yi.

# IYAAFIN AWO FẸ ṢE IBẸWO AWỌN ENIA IWỌ — ORUN

IBADAN:- Ni deede agogo mẹwa alẹ ana ọjo Aiku ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Irohin kan de si etigbọ wa wipe, Oloye Iyaafin H. I. D. Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) yio bẹrẹ Irinajo ibẹwo gbogbo awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria fun ọjọ marun ni deede agogo mẹwa Owurọ yi pẹlu gbogbo awọn Obinrin sarakisaraki ninu ẹgbẹ na.

Irohin fi ye wa pe lati alẹ ana ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti yio ba Iyafin Awolọwọ lọ si irinajo na ti bẹrẹsi de si Ibadan ni Oke — Ado ninu ile Oloye Awolọwọ lati ma mura silẹ fun ibẹwo na.

Onirohin wa, Ejongboro ti o wa ni Ibadan fi ye wa pe, odidi wakati meji ni awọn enia ko le ri ọna kọja nigbati awọn alejo na bẹrẹsi de si Oke - Ado.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, Oniwe Irohin wa fi ye wa pe awọn mọto ayọkẹlẹ ti yio tẹle Iyaafin Awolọwọ ni owurọ yi lọ si irinajo na le ni ọgọta. Gbogbo wọn si ti mura silẹ fun irinajo ni owurọ yi.

Ninu awọn enia jankanjankan ti yio ba Iyaafin Oloye Awolọwọ lọ si irinajo na ni owurọ yi ni:-

Iyaafin Fẹmi Pearse, Iyaafin Abiba, Iyaafin Magaji Obisesan, ẹniti gbogbo aiye ma orukọ adape rẹ "Sisi Ghana" Iyaafin S T. Ọshọba, Iyaafin Ajurin. Iyaafin Ṣebọlatan, Iyaafin Ọdẹku, Iyaafin Adegbenro, Iyaafin Aluko, Iyaafin Ige, Iyaafin Agunbiade - Bamshe, Iyaafin Ọrẹdẹhin ati Ọpọlọpọ awọn enia miran.

Irohin fi ye wa pe,



IYAAFIN H. I. D. AWOLỌWỌ

ni deede agogo mẹsan owurọ yi ni awọn enia na yio kuro ni Ibadan lọ si irinajo ibẹwo wọn

Ninu awọn ilu ti nwọn o de ti nwọn o si ba awọn enia sọrọ ni awọn ilu bi, Ondo, Akurẹ, Ejigbo, Oshogbo, Ile-Ifẹ, Ilesha, Ikarẹ, Ẹdẹ, Ọwọ, Iwo ati awọn ilu ti o wa ni agbegbe wọn.

Ninu gbogbo awọn ilu wọnyi, ni Oloye Iyaafin Awolọwọ yio ti ba awọn enia sọrọ lori bi gbogbo nkan ti ṣe nlọ si ni Ipinlẹ yi ni asiko yi,

Irohin ti a ri gbọ lati ọyọ ati Awẹ ni alẹ ana fi ye wa pe, awọn ara Ilu ti ta asia yika gbogbo arin ilu, ti nwọn si tun arin ilu ṣe, gbogbo wọn si nreti Iyaafin Oloye Awolọwọ.

A gbọ wipe pẹlu ilu, ṣẹkẹrẹ ati ijo ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre Awẹ yio fi lọ pade Iyaafin Awolọwọ ni Odo Asaba, ti gbogbo wọn yio si jo wọ arin ilu

Iyaafin Awolọwọ ṣe alaye fun Oniwe irohin wa pe, On ti lọ si Kalaba lati lọ bẹ Oloye Awolọwọ wo, alafia ati ara lile lo wa, On si fẹ jiṣẹ Oloye na fun gbogbo awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun ki nwọn fi ọkan balẹ.

Ki gbogbo wọn duro laimikan ki nwọn o si ni ireti. O tun ṣe alaye pe "Enia gbọdọ ri Adawo ati oke iṣoro-iṣoro nile aiye ẹniti o ba fi ori ti dopin ni ao gbala Ẹniti o ba si rẹrin gbẹhin, On lo rẹsin to dara julọ. Ọpa agbelejika tẹhin lo ju, atipe bi ẹkun ba pẹ titi de Alẹ ayọ mbọ ni Owurọ"

Iyaafin Oloye Awolọwọ ba ipade gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ sọrọ ni Ibadan ni irọlẹ ijẹta ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kedogun oṣu yi.

Ninu ọrọ rẹ, Iyaafin Awolọwọ ṣe alaye ọrọ ti Iyaafin Faderea Akintọla sọ gẹgẹbi ọrọ "ojo enia" pe ẹgbẹ Afẹnifẹre fi ẹdẹgbẹta ọkẹ pọnun (£10,000-000.) pọnun si Banki kan ni ilu Oyinbo.

Iyaafin Awolọwọ ni bi ọrọ na ba jẹ ododo kiniṣe ti Oloye Akintọla ati awọn enia rẹ ko sọrọ na niwaju igbimọ Oluwadi Oloye Coker nigbati o fi nṣe iwadi eto inawo nkan ni Ipinlẹ yi ninu ọdun keji to kọja

O wa bere pe, "kini ṣe ti Okete Akintọla de ẹhin aro tan ti o wa ka ọwọ soke ọwọ ti ko le ka soke si Ọdẹ ninu igbo?

Iyaafin Awolọwọ ni gbogbo ọrọ ti Iyaafin Akintọla nsọ kakiri yi, kọni awọn enia nfẹ. O ni ohun ti awọn enia Ipinlẹ yi nfẹ ni asiko yi ni Ibo atundi si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Gbogbo enia lo kigbe "Awo! Awo!! Zik! Zik!!" nigbati Iyaafin Awolọwọ sọpe "Bi nwọn ba tu Ile Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun a loni ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakọ yio wọle.

Woju Ewe Kẹfa.

# Ẹ FI ỌKAN FẸ AWOLỌWỌ

Owe ti ngo fi kia Ọgbẹni Moshudi Ademosun lẹhin lori ikilọ rẹ to ṣe fun awa Ọmọ Yoruba nipa ibosi Awo! Awo!! ti a nke kiri ilu to jade ninu "Irohin-Imọlẹ ti ọjọ kẹfa oṣu August 1964 ni owe awọn baba nla wa to sọ wipe:- "Oko ti a o ba fi pa iyẹ Ẹlẹgiri, labẹ aṣọ ẹni lo ngbe," Ki owe na o jẹ ti ẹnyin Onkawe.

## Lati Ọwọ Erukobodo Eko

Mo dupẹ lọwọ Ọgbẹni Ademosun fun ọgbọn ati lakaye rẹ ti o fi ba awa ọmọ Yoruba sọrọ nipa igbe nii okiki Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ to mbẹ ninu Tubu loni ti a nke kiri, eyiti emi papa ri i daju wipe ohun ti ibosi ati igbe Awolọwọ ti a nke kiri ti da si'e ko kere.

Mo mọ daju wipe tinu-ti nu ni ọmọ Yoruba fi nfẹ Ọlọla Awolọwọ ati pe, nwọn nfẹ ẹ ni alakoso, tabi ni Olugbala ilẹ Naijiria fun igboiya ati otitọ ti o ti nfi nṣe oṣelu bọ lati ẹhin wa, ṣugbọn mo fẹ ki ẹnyin Ọmọ Yoruba ranti owe awọn baba wa kan to sọ wipe- "Bi o ba ṣe wipe, bi Ọrun ti tobi to ni a o fi bu okele, mo ri i daju pe Onigegẹ iba bu okele iyan tawo-tawo" Itumọ owe mi yi ni wipe, bi o ba ṣe wipe, bi tọmọde-tagba nilẹ Naijiria ti fẹran Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ to ni a o fi ma p longo rẹ "Oṣika yio d'oju iwe dele" nitori pe "Bi koko nfẹni lẹfọ, a ki i jẹ ori Imado, b a ba si jẹ ori Imad , awujọ kumọ ni a k) gbọdọ de".

### Ẹ FI ỌKAN NYIN BAMILO

Ohun pataki ti mo fẹ sọ fun ẹnyin Ojulowo ọmọ Yoruba ti ọran Awolọwọ ndun ni wipe, ko to ki a ma a ṣe ohun kan, ki a maṣe ma ranti asọtẹlẹ. Bi ẹ ba gbagbe, ngo ran nyin leti asọtẹlẹ ti Ọlọla Awolọwọ sọ fun tọmọde tagba wa ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu May 1962 ni gbangba Ode ni Isalẹgangan l'Eko, eyiti o sọ wipe, Nwọn ti fi Ankọfu tabi, Mamugari si on lọwọ, Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ nsọ ni a sọ yanju ni ọjọ na wipe Ọwọ on ni enia le fi Ankọfu ti, kosi ẹniti o le fi Ankọfu mu ọkan on. O tun nsọ ni a sọ ye fun enikẹni gbọ lọjọ na wipe- Bi nwọn ba mu on lọ, ohun ti on nfẹ ki ẹnyin Ọmọ Yoruba to jẹ Ọmọ ẹgbẹ on ṣe ni wipe - Ẹko gbọdọ ja, bẹni ẹ ko gbọdọ pariwo, ọkan yin ni ki ẹ ma fi ba on lọ si ib ikibi ti nwọn nba mu on lọ.



Ọgbẹni ẸRUKOBODO



Oloye AWOLỌWỌ

### MARIWO TO NSẸLẸYA

Nigbati a ti gbọ bẹ tẹlẹ kini ohun ti o tun le mu wa ma fi pariwo Awo!Awo! nigbati a ti ri i wipe ikorira ni Orukọ Awo! ti da leti eṣika? Kiniṣe ti ẹ ko jẹki a pa ofin "Awo" na mọ ki a gba kadara ati pe, ki a fi ija fun Ọlọrun ja, ki a fi ọwọ wa leran, ki a ma a wo igbẹhin' gẹgẹbi ẹ ti mọ ti ohun ti a ti ngbọ lẹnu awọn baba nla wa wipe- Mariwo ọpẹ ti o nfi igbago ṣẹsin, on na mbọ wa di ohun agbelẹ he"

### ALA AWO YIO ṢẸ

Nitotọ ni aiye nfẹ Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, ti ero Ọrun tun nfẹ pelu, Ṣugbọn, ọ jẹki aran lọwọ nipa idakẹ jẹ ti okun fun Adura Atọkanwa ati pe, o tọ, ki ama ranti ọrọ awọn Babi wa kan to sọ wipe - "Bi Iṣu ẹni ba ta ti asi njẹ ti o dun leou, ọwọ loyẹ ki ama fi bo o ki ato jẹ ẹ"

Bi aiye ti nfẹ Awolọwọ to, mo ri daju abangba wi re bi enikẹni ko jade fun ipolowo Idibo, kosi Ibo kan ti ao di nilẹ Naijiria ti Ọlọla Awolọwọ koni wọle, nitoripe, Ọkan ẹni ni ni Alufa ẹni

Nipari ọrọ mi, Ọkan nyin ni ki ẹma nifẹ Awolọwọ, ẹjẹki a ṣiṣọ Ariwo ki Ala rẹ ọjọ kini lẹ ṣẹ.

# Yẹyẹnatu

## Oniyẹyẹ Eko

Yẹyẹnatu: Olotu, ẹ jọwọ ẹ ba wa bẹ wọn

Olotu: Awọn wo niyẹn kẹ?

Yẹyẹnatu:- Ha, ẹ tun nbi mi. Tabi ẹnyin na wa wọn. A bi ọmọ ninu ni ile ifẹ, o nja ifẹ logun

Olotu.- Mo mọ alọ yẹn kẹ

Yẹyẹnatu Mo mọ pe ẹ mọ ọ na ni O dara kini?

Olotu:- Ṣebi igba ti nwọn nfi gun ọpẹ ni.

Yẹyẹnatu:- Yẹs, ẹ mọ lo-ọtọ.

Olotu:- Ẹni ba si gbọ ti ko ba mọ a ro pe ọrọ ti Ọni ni a nsọ.

Yẹyẹnatu:- Sebi baba gbogbo wa ni Ọni, ṣebi kab'yesi ni baba agba Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ati Ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin.

Olotu:- Iyẹn lo ṣe ya wa lẹnu pe nwọn nda baba wa laamu.

Yẹyẹnatu:- O maṣe o. kabiyesi tun di ẹniti nkesi ẹnikan ko gba on silẹ.

Olotu:- Ilaju ni yẹn ke.

Yẹyẹnatu:- Ati pe bi Okete ba dagba ọmu ọmọ rẹ lo nmu.

Olotu:- Ko sirọ nibẹ.

Yẹyẹnatu:- Ṣe Akintola ti sọ pe Ẹgbẹ Alajọbi ni NNDP, nitorina ni ẹgbẹ Dọmọnu ṣe nṣe bẹ. Ṣe alajọbi lo ndajọ

Yẹyẹnatu:- Yẹs kẹ, a ti ẹniti ko le farabalẹ ba ọmọ rẹ ṣe iyawo, ati ẹniti nwọn nfọ mọto mọ lori.

Olotu:- O maṣe o.

Yeyenatu:- Olotu ẹ kẹ sọ fun lagbaja wi pe obinrin ko ṣe ba ṣe awo.

Olotu:- Tani lagbaja? awo ewo?

Yeyenatu:- Lagbaja ba tamẹdu ṣe ipade ẹnu iyawo lagbaja lati gbọ ohun wọn ṣe.

Olotu:- Ha, iwọ ko ma laju o. Laiye ọlaju yi, ohun tokọ ba gbọ iyawo lo gbọ yẹn kẹ.

Yeyenatu:- O maṣe o. Abajọ ti a tete ma ngbọ iso ijọba ki o to jade ni idi wọn.

Olotu:- Ẹjọ rẹ niyẹn. Ma ko ba mi,

Yeyenatu:- Ẹru nba yin ni awọn ọba nikan ni ẹru nba nisisiyi nitori eyiti nwọn ko ge owo rẹ ku kọbọ ọdun, nwọn a le kuro lori oye.

Olotu:- Gbogbo oba ko ṣa

Yeyenatu:- Yes gbogbo ọba kọ. Adele ti bọ lọwọ. won, Olubadan Oiogbe si ti bọ.

Olotu:- O ku awọn kan laiye to ti bọ.

Yeyenatu:- Ṣe awọn biawọn to n'a idi awọn oṣelu ntori ko wo wọn ma di kọbọ.

Olotu:- Ṣe iwọ le bọ wọn ni

Yeyenatu:- Nko to bẹ ṣugbọn awọn na ko le' bọ mọ.

Olotu:- O jẹ yara pẹnu rẹ mi.

Yẹyenatu:- Tabi a ko gbọdọ sọrọ mọ o dara o dabọ o.

## Otęlęmuyę Eko

Otęlemuyę nki nyin o, ę o ni ba aladugbo bubuiu gbe o, ęni ęlęri ko ni gba işe uyin şe o lagbara Baba loke. Mo ti nko orisirisi ọrọ sinu iwe ọjọ ti pę iwasu gan ni mo si fe şe fun nyin ni ose yi, mo fę ki ę fi tọkan tọkan ki ę si ma fi şe iwa hu, nitoripe Ọpọlọpọ ęda lo fęran lati ma se keeta ọmọ enikeji rę, lati ma sọ ọrọ ibajẹ lẹhin ati lati mura ni ona-kọra lati dọwọ rę dele ę da iwa bubuiu duro nitoripe Oluwa ko ni inu didun si.

ĘSAN KOGBOGUN

Esan ko gbogun ọrę mi
O pę o ya
Esan yio ke dandan
Agbalagba ti o ba gbin ebu ika
Ọmọ rę yio ję nibę dandan
Iwọ Abaniję
Ti a ko baję
Nigbati iwọ ba
Dękun ati baniję
Nigbana ni a o ba ọ ję
Ęniti O şe rere
o se fun ara rę
Ęni ti o şe ika
O şe fun ara rę
Ore ati ika
Ọkan ki gbe
A f o j u ma fọ kan ęni
A şe ni ba ni daro aladugbo,
Ranti pe ęsan yio bę dandan lori rę.

Buburu lo mọ şe ni
Rere lo mọ şe ni
Ranti pe ọjọ kan nbọ
Ti iwọ yio jihi fun Ęlęda rę
Iwọ ma ję ki tę ni suwọn
Onile ori oke
Tę ni ma suawọn ki gbọ
Ęyin ti ę nlo afọşę
Fun ọmọ lọmọ ni ęnu işę
Ę ranti ęsan o
La'otan ara
Ęgbinyanju lati ma se rere
si ọmọ ni keji nyin
Nitoripe ohun ti Oluwa ni fę si ni eyi
Nko sọ wipe ki ę fęran
Ęniti o ba fę se nyin ni ibi
Ofin Bibeli ni
Bi wọn ba ju ọ ni okuta
Ju Idarọ lu wọn o
Ohun ti mo wi ni wipe

---

## YE IRAWỌ RE WO

AGUARIUS (Jan 22-Feb 20) Bi nwọn ba pe ọ sibi Aşeyę kan, ma aşiko nitori pe ibę ni iwọ yio ti ba awọn enia pataki pade lati ibę ni iwọ yio ti de Ipo giga.

PISCE (Feb 21-Mar 20) Iru Ipo ti owa loni, ko tę ọ lọrun rara, osi ję ohuu to ru ọ loju eşe ti iwọ ko fi gaju bę lọ?

ARIES (Mar 21 - April 20) oda bi ęni wipe nkan ko ri gęgębi o ti şe ma nri fun ọ, tęlę ri Iwọ yio gbọ irohin kan ti yio mu inu rę dun sa jęki ọkan rę mọ, ki o si ma lepa inu rere.

TAURUS (April 21- May 21) Ijọngbọn kan nfi dugbę-dugbę niwaju rę, wa iranlọwọ awọn ęlomiran, ki o ba le bori rę Obinrin ajeji kan yio wa bę ọ wo loni gba ni alejo daradara ire yio si tibę jade.

GEMINN (May 22 - June 21) Maşe pọn ara rę pe ko si bi iwọ ko ti ri, Bi oba dubulę ti osun dię, arę ara yio folọ, Bibę si kọ ewę, ole şe ere idaraya dię (Exercise)

CANCER (June 22 - Jly 23 Ọrọlọpọ igba ni oti ma nyę ọrọ kan ti aye wa fun ọ ninu eyiti o le latęsiwaju ninu awọn ohun ti o ngbero ninu ọkan rę Bi oba şe bę ire y o tilę yọ si ọ lọpọlọpọ.

LEO (July 24-Aug 22) Gba imọran ti awọn ọrę rę tabi ojulumọ rę fun ọ fi si ọwọ osi mase fi jęka nitoripe ọkan ninu awọn alagbara rę yio yi ọ si okolombo jikolombo.

Virgo (Aug 23-Sept 23) Ọgbọn ori rę ti pe to lati se ohun kohun ti o ba wu ọ lati se laiwa iranlowọ lati ọdọ ęlomiran nitorina awọn ọrę rę kowa ire fun ọ bo le baję ko baję ni wọn nwa fun o.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Edekoyede kan yio bę silę larin iwọ pęlu obinrin ti o nfę ọrọ na yio si fę di ija, Ohun ti o dara fun ọ nipe ki o yara tete pero si ọrọ na ki ija na le tan nilę

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 22) Ara rę ko l e to lati ba ọkọlokoji rę ta pero nipa işę, n ş e n i ki o şebi ọkunrin dajudaju iwọ yio si bori.

SAGITTARUS (Nov. 23-Dec. 21) Ailera enia rę kan ndun ọ lọkan, mu lọ si ọdọ onişegun yio si ri iwosan, şugbọn ko maşe sişę ti o le fun igba dię alafia ara yio si de si ọ.

CAPRICORN (Dec. 22-Jan. 21) Adanwo kan yio de si ọ ninu eyiti iwọ yio fi ba nkan a r a rę ję fa wọn enia mọra iwọ yio si gbadun awọn ọrę ti o ni.


## EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



"CYCLOVN"

Aworan ęgbęyi fihan gbangba ibiti Jędijędi rę ba wa ara rę si nyọ ọ lęnu nigba gbogbo. Ibę ni a n p e ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma be şe igbọnşę Arun Jędijędi ję ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si lagbara pupọ la i ş e iwosan r ę patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti nwọn ma a polowo w ọ n un iwosan rę şugbọn boya la leri mewa ninu a w ọ n ogun ni o le şe iwoşan arun yi daradara, Awọn ęlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile iwosan lati lọ ke eyiti oba nyọ jade lati omusu ku nipa bę awọn o bọ lọwọ rę patapata.

Şugbọn awa ko ro bę rara lęhin ọdun dię iyọnu rę yio si tun bęrę bakana Orisirisi Jędijędi ni o wa, Ekini ti o bęrę nipa aiko ma şe igbọsę dede tabi lojojumọ ęlomiran nipa ijoko ni (jukanna fupọ ojojumọ tabi gigun kękę ologere (Basikulu) pupọ ęlomiran ewę fęran Şuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jędijędi di orisirisi ni o wa, ewo ni tirę? Bi o nyọ jade ninu omuşu tabi ti o ba nmu ęję wa lęhin igbọnsę tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnşę tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o ba ję bere egbogi CYCLOVEN ti awọn Oyinbo Jamani şęşę wa idi rę kio si danwo risi i me a daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jędijędi patapata alafia lo de ọ ekeji rę ko si ninu gbogbo egbog atata nigboro Naijiria bere ni:

NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Adedun Chemist
14, Workeman Street, Yaba



# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patronise* M O D U P E P R E S S
*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

## Modupę Prnting Press

**16 Bamgbose Stree**
85, Lagos

# Eyi ni awọn ọjọ Oja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE AUGUST 17 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBERẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Ibẹrẹkoko, Aṣu, Wasinm, Ow ode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ Ogunjau Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu Ogere Irolu Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla Imẹsi-Ile Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunwa |
| ẸGBADO | Iboro |
| EKITI | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ IṢẸGUN AUGUST 18 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ọbun—Eko, Ojuwoye, Ikosi Ẹpẹ Atan, Agbabo, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Pẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta, Ijaiyẹ—Orilẹ |
| IJẸSHA | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe Iṣara, Imọdi, Ishan, Akẹsan, Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ |
| IJẸSHA | Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiye toro, Adc—Odo |
| EKITI | Igosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ'RU AUGUST 19 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagry |
| ABẸOKUT | Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ Omi Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwn Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBA DO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ AUGUST 20 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajọ Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọ |
| ABẸOKUTA | Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo- |
| IBADAN | Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha Iwara Ejiro, Odo, Ibokun, |
| ẸGBADO | Lasilo Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ẸTI AUGUST 21 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUT | Ijoko, Ibẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akero o, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjau, Motẹlẹlẹ, |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaoṣu Ogere, Irolu, Itelu Ode-Rẹmọ Oyingbo |
| JẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile Alagba, Ilaro, Ọja- Ọdan, Sunw |
| ẸGBADO | Iboro |
| EKITI | Ilog o, Ishan. |

## ỌJỌ ABAMẸTA AUGUST 22 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Iṣabọ Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| BADAN | Fẹdẹgbo, Oyededeji Ogburo, Ẹgbẹ Babalokuta. Ijaiye-Ọrile |
| IJẸBU | Ilishan, Iṣara, Imodi. |
| IJẸSHA | Ẹpẹ Iọbnlmuroko, Erinm |
| ẸGBADO | Ayetoro Ado-Odo |
| EKITI | Egosi Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ AIKU AUGUST 23 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Mushin, Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ, Omi Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun —Ọwa, Ẹruwọ Omu. Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko Itoko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AJE AUGUST 24 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ikẹja, Agege Ebute—Ikorodu Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imode |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilọ-Idiẹmi |
| EKITI | kemẹsi, Ifaki. |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ ƐJO'NGBORO

### ENUGU

Awọn ọmọde mẹtadinlọgbọn ni ile ejọ awọn ọdọ ti Enugu ni ipinlẹ Ila Orun Naijiria ni ile ẹjọ na ṣe ejọ fun ni osu to kọja yi eyiti ile iṣẹ alabojuto alafia awọn ọmọde ṣẹṣẹ te jade ni ile iṣẹ Alakoso eto alafia ilu ti Ijọba ipinlẹ Ila Orun Naijiria bayi.

### IBADAN

Ile ẹjọ kekere ti Ibadan ti gbe idajọ ẹjọ apania kan ti ile ejo na fi kan ọdaran kan Muhamman Katsina fun ẹsun pe o fe pa ọmọde kekere okunrin kan Amusa Salami eyiti ile ẹjọ na sun ẹjọ na si ọgbọnjọ osu ti nbọ Awọn ọlọpa si ti fi Ọkunrin ọdaran na lọ pamọ si ọgba ẹwọn titi nwọn yio fi ṣe ẹjọ ra.

### IJAKARAT

Ilẹ Indonesia kọ ile iṣẹ ni ọkọ Ofurufu kan eyiti iye owo to pari rẹ jẹ £390,000 ni Malama ni ipinlẹ Ila Orun Java Irohin na de etigbọ wa lati inu iwe irohin wọn kan ti a npe ni Antara, Ile iṣẹ ofurufu na si ti gba awọn oṣiṣẹ ti o mo nipa iṣẹ ọkọ Ofurufu to bi ẹdẹgberin enia (700) ati awọn enia kan ti nwọn tun jẹ ọkan ninu awọn to mọ nipa iṣẹ na.

### TAIPEI

Ninu eto kika enia kan ti nwọn ṣe ni Ilu Taiwaos ti ojẹ olu ilu fun Taipei fi han pe awon enia ti ngbe ni Orilẹ na jẹ 12,000,000, Awọn Obinrin to wa ni ilu na le jẹ bakanna ninu eto enia kika na ati pe gẹgẹbi eto enia kika na ti nwọn ti ṣe ninu oṣu kẹfa ọdun yi eyiti nwon ṣẹṣẹ gbe abayọri rẹ jade bayi

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 772. MONDAY, AUGUST 17 1964 (2D)


## Awọn Obinrin Onişowo Ijẹbu Ode Ti I'ada Si Isọ wọn

IJẸBU-ODE:- Ni ọjọ Abameta t' ise ọjọ kẹdogun osu yi ni irohin de ọwọ wa lati ọwọ oniwe irohin pe awọn obinrin onisowo ti ilu Ijẹbu Ode ati agbegbe rẹ ti oko ọja Ita -osu silẹ lai ta nkan-kan ni irohin fi ye wa pe awọn obinrin na ti pada si isọ ibi ti nwọn ti nta . kan bayi.

Irohin na fi ye wa pe awọn obinrin onisowo na pada si ọja lati lọ ma ta awọn ọja wọn lori ipade kan ti Ọba Awoyale ti ilẹ Ijẹbu, Ọba Sikiru Adetọna şe pẹlu awọn Ijoye rẹ pẹlu awọn Aşoju awọn onisawo na lati le dekun rogbodi- \an to sẹlẹ larin awọn obinrin onisowo ati awọn ibbimọ Afunshọ tı Ijọba Ibilẹ ilu Ijọba ode lori aworan awọn onisowo kekere ti nwọn sọ pe ki nwọn şe lati le fun wọn ni işọ eyiti awọn obinrin na taku pe awọ ko ni şe ati pe eto lati le jẹ ki nwọn şe ẹgbẹ Dẹmọ pelu ipa ni'

Awọn igbimọ Afunshọ ti Ijọba ibilẹ na ko lọ sibi ipade na sugbọn oba Adetọna tl sọ pe on yio ri awọn igbimọ na lati ba wọn şọrọ Awọn Ọlọmọlake ati awọn Alapata ti o npa ẹran malu si ti bẹrẹ isẹ won bayi lati le dẹkun airi onjẹ jẹ ni ilu Ijọba- Ọde ati agbegbe rẹ.

# ỌKUNRIN KAN KU NI ỌJỌ IGBEYAWO RẸ!

## Awọn Alabaşe Bẹlugbẹ

MAIDUGURI:— Jinnijinni dabo gbogbo enia tì, Okele ẹba si bọ lọwọ awọn ẹlomiran nibiti nwọn gbe nrẹrin nidi onjẹ aşe igbeyawo Ọgbẹni Malam Busa Danlaye ti o pe wọn wa sibi igbeyawo rẹ ni ilu kan ni Adam kolo ni agbegbe Maiduguri,, ti ọkọ iyawo na si ku nibiti awọn enia ti nyọ ayọ igbeyawo ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kẹdogun oşu yi.

Ẹniti ọrọ na soju rẹ, ọkan ninu awọn ọrẹ ọkọ iyawo na ti o ku şe alaye fun oniwe Irohin wa to wa ni Maiduguri pe, Mallam Busa Danlaye ti da ọjọ iyawo rẹ si ọna. ti o si sọ fun awọn nigbati o ti ku oşu mẹta

Nigbati ọjọ iyawo ku ọjọ mejila ni gbogbo awọn ẹbi ati ọrẹ pẹlu awọn ẹgbẹ ọkọ iyawo ti da aşọ igbeyawo, ti awọn si nşe imura silẹ ọjọ iyọ na.

O tun şe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe, işẹ obi tita ni Malam Busa nşe ni ọja, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ olobi Ọja Maiduguri ni nwọn tı da Aşọ ti awọn si tun da Owo jọ fun Busa ti awọn fẹ fun un ni ọjọ Igbeyawo,

Şugbọn nigbati awọn de ibi Igbeyawo na, ti awọn si ba awọn enia, ti nwọn nję, ti nwọn nmun ti awọn onilu si nlu Ilu wọn ni ẹkọkan ti gbogbo rẹ ndun Yungba,

Lẹsẹkẹsẹ ni ọkọ iyawo ba sare wọle bi o ti ri awọn ti o si lọ gbe onjẹ ẹgbẹ awọn na,

Nigbati awọn ti njeun lọ wọ, ui awọn ẹgbẹ miran tun jo de . pẹlu aşọ igbeyawo, Bi awọn enia na ti njo, ni awọn ndide ni ọkankan ti awọn si ufi owo mọ wọn lori Ti ariwo ilu ko jẹki awọn gbọ ariwo enia, bi ọkọ iyawo ti nwọle, bẹni o njade.

Şugbọn nigbati awọn enia fẹ di awọn lọwọ nibiti awọn ẹgbẹ ọkọ iyawo fẹ gbe jeun, ni awọn ba dide kuro nibẹ, ti awọn si bọsi ẹgbẹ keji, ni gbangba ode lati ma a jẹun,

Şubọn bi ọkọ iyawo ti dupẹ lọwọ awọn tan, ti o si kuro lọdọ awọn, ni o ba wọ inu iyara rẹ lọ, o si sọ fnu awọn pe, ki awọn tete jẹun tan, ki awọn ti yio mu i y a w o wale to de, ki nwọn o ma şe ba awọn nidi onjẹ.

Şugbọn bi ọkọ Iyawo ti jade wọ inu Iyara ti osi ti Ilẹkun mọri pe ki on lọ mura, ni awọn ba reti ati jade rẹ ti awọn ko si ri i ki o jade,

Awọn kan ilẹkun, awọn ko gbọ ohun rẹ, awọn lere lọdọ awọn ti o duro si Ọdẹdẹ, awọn sọ fun awọn pe o wa nile, awọn pe awọn ko da awọn lohun ni awọn ba fi ipa şi Ilẹkun, Oku rẹ ni awọn ba nilẹ ti o si ti ku Bamubamu.

Ọrọ di bolọ o ya ngmi ni gbati irohin de etigbọ gbogbo awọn enia pe ọkọ iyawo ku, ariwo ijo ati ilu wọ lẹ şin in !

Awọn ẹlomiran ti salọ, awọn miran duro lati şe itọju ọkọ iyawo na.

Irohin fi ye wa pe, nigbati irohin iku na de ọdọ iyawo nibiti nwọn gbe ngmura fun un lati wa si ile ọkọ rẹ, nşe lo şubu lojiji ti o si daku.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe Iyawo na lọ si Ile-Iwosan fun itọju. Nigbati oju iyawo na walẹ tan, O şe alaye fun Oniwe Irohin wa pe Ori on bu u Ọkọ on ku ni Ọjọ Igbeyawo !

Gbogbo onjẹ ti nwọn toju silẹ ati aşọ ti nwon fi nşe Isinku.

Ninu awọn ọrẹ rẹ na, ni nwọn ba duro ti nwọn si gbe Oku rẹ lọsin ni ọjọ na.

Iyawo na şe alaye fun oniwe irohin wa pe, on ko mọ bi aiye ni on wa bi ọrun ni, iyawo na ko ti le jẹun titi di igbati a fi nkọwe yi.

Awọn ọlọpa si ti nşe iwadi iku ti o pa Ọkunrin na lọwọ. OLUWA RERE, GBA WA LỌWỌ IKU OJIJI O. (Amio)

### LATI OJU EWE KINI

Iyaafin Awolọwọ ni 'gbogbo awọn ara ilu lọ ti mọ awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni Ọdalẹ, ti o fi ẹnu Şalẹjẹ ka kiri ibiti nwọn ba gbe le ri onjẹ jẹ, ibi yowun ti onjẹ na le ti wa wọn ko kọ, nwọn ko si bikıta lati gba''

O tun sọ siwaju pe, ''ni gbati awọn ọmọ ẹgbẹ na mọ pe, awọn enia ko ni igbekẹle si awọn, nwọn wa bẹrẹsi p'lowo ẹgbẹ wọn ninu ẹrọ Redio''

Ni gbogbo ibiti on de ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ ti sọ lori ẹrọ Redio pe, nwọn di ẹgbẹ Dẹmọ ni nwọn nsọ fun on pe, ko si ẹniti o şe ipade larin ilu ti nwọn fi mọ ẹgbẹ ti awọn nşe, a fi bi awọn ti şe ngbọ lati ori ẹrọ Redio.

O ni gbogbo awọn ara ilu ni nwọn nsọ p., Bi ẹgbẹ Dẹmọ ni awọn nsọ bi ti Afẹnifẹre ni, nigbati asiko ibo ba de, gbogbo aiye ni yio mọ, ki awọn si fara balẹ, ki awọn si ma a woran, ohunti yio şelẹ.

Irohin fi ye pe ni ọjọ maruu oni awọ enia na yio pari ibẹwo wọn ti gbogbo wọn yio si pada si Ibadun, Ki Ọlọrun mu wọn lọ layọ ki o si mu wọn bọ ni alafia o. Amin.



OLOYE AWOLỌWỌ


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 17/8/64.